# IGBALA NIPA IGBAGBỌ́

**Romu 4:1-25; Gẹnẹsisi 12:1-3; 15:6**

**ẸKỌ 383 -- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Ibukún ni fun awọn ẹniti a dari irekọja wọn jì, ti a si bò ẹ̀ṣẹ wọn mọlẹ" (Romu 4:7).**

### Iwe

Iwe Romu jẹ́ iwe ti Paulu kọ si awọn Onigbagbọ́ ti o n gbé ni ilu Romu. O kọ iwe si wọn nipa igbala, ibi titun (didi atunbi), eyi ti i ṣe iṣisẹ kin-in-ni ninu jijẹ ọmọ-ẹyin Jesu. Ọpọlọpọ igba ni a n gbọ iwaasu nipa igbala lọjọ oni. Wọn jẹ́ iranlọwọ pupọ fun gbogbo awọn ti o n gbọ́ wọn. Awọn ti a ti gbala a maa gba itọni lati sọ nipa igbala. Awọn ti kò si ti i ri igbala n kọ́ bi a ṣe le ri igbala a si n gbà wọn niyanju lati wá igbala.

### Olododo

Paulu tun ọrọ Wolii Habakkuku sọ, wi pe, "Olododo yio wà nipa igbagbọ́" (Romu 1:17). "Awọn olododo" ni awọn ti a dalare ti wọn si jẹ olododo. Lati jẹ́ ẹni ti a dalare ni pe ki a bọ́ lọwọ ẹbi. Orukọ miiran ni eyi fun iriri igbala. Eniyan ni lati ni igbagbọ́ ki o to le ri igbala. Olododo ní lati nai igbagbọ ki agbara Ọlọrun ba le pa a mọ́.

### Apẹẹrẹ

Abrahamu jẹ́ apẹẹrẹ ẹni ti a dalare nipa igbagbọ́ -- ẹni ti a gbala nitori pe o ni igbagbọ́. Gbogbo awọn Ju ni o n tọka si Abrahamu gẹgẹ bi baba wọn. Oun ni ẹni ti Ọlọrun pe lati ilẹ Uri ti Kaldea ati lọ si Ilẹ Kenaani (Gẹnẹsisi 11:31). Ileri iyanu kan tun jade pẹlu ipe yii pe Ọlọrun yoo sọ ọ di orilẹ-ede. Ọlọrun wi pe ninu Abrahamu ni a o ti bukun-fún "gbogbo idile-aiye." Eyi yii jẹ majẹmu tabi adehun laaarin Ọlọrun ati Abrahamu.

### Si Kenaani

Abrahamu gbọran si aṣẹ Ọlọrun, o si bẹrẹ irin ajo rẹ̀ pẹlu ẹbi rẹ̀ lọ si Kenaani, ilẹ ileri. Abrahamu mu ipa ti rẹ̀ ṣẹ ninu adehun naa pẹlu Ọlọrun nigba ti o lọ si Kenaani. Ṣugbọn fun ọ̀pọlọpọ ọdún lẹyin eyi, oun kò ri imuṣẹ ileri Ọlọrun. Abrahamu gba Ọlọrun gbọ́ o si ni igbẹkẹle ninu Rẹ̀. Abrahamu gbọran si aṣẹ Ọlọrun eyi si ran igbagbọ́ rẹ̀ lọwọ.

### Gbigba Ọlọrun Gbọ́

Nigba ti ẹlẹṣẹ ba lọ si ibi pẹpẹ lati gbadura yoo gba pe oun ti ṣe aitọ́, yoo ronupiwada awọn ẹṣẹ rẹ̀, yoo si bẹbẹ fun idariji. Nigba ti o ba gba Ọlọrun gbọ́ ti o si gba ileri Rẹ̀ gbọ́, yoo ri igbala. Ẹlomiran le kaanu fun ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ki o si bẹbẹ fun idariji, ṣugbọn bi kò ba gba Ọlọrun gbọ́, a ki yoo gba ọkan rẹ̀ là.

### Igbagbọ́ ninu Ọlọrun

Diẹ ninu Ọrọ Bibeli Mimọ́ ti o n fi hàn wa pe a ni lati ni igbagbọ́ ninu Ọlọrun ni wọnyii. "Ṣugbọn li aisi igbagbọ́ ko ṣe iṣe lati wù u (Ọlọrun); nitori ẹniti o ba ntọ̀ Ọlọrun wá ko le ṣai gbagbọ pe o mbẹ, ati pe on ni oluṣẹsan fun awọn ti o fi ara balẹ wá a" (Heberu 11:6). "Ohunkohun gbogbo ti ẹnyin ba bère ninu adura pẹlu igbagbọ́ ẹnyin o ri gbà" (Matteu 21:22).

### Bi Irawọ

Lẹyin ti Abrahamu ti wà ni Ilẹ Kenaani fun igba diẹ, Ọlọrun fi ara hàn an. Abrahamu rán Ọlọrun leti nipa ileri Rẹ̀, o si sọ fun Un pe oun kò ni ọmọ. O le jẹ pe Abrahamu n rò ninu ọkan rẹ̀ bi oun yoo ṣe le di orilẹ-ede kan. Ọlọrun tun ileri Rẹ̀ ṣe. O sọ fun Abrahamu pe ki o wo awọn irawọ oju ọrun bi o ba le kà wọn. Nigba naa ni Ọlọrun wi pe idile Abrahamu yoo pọ̀ bi irawọ. Ọlọrun ṣeleri ọmọkunrin kan fun Abrahamu. Abrahamu "si gba OLUWA gbọ́; on si kà a si fun u li ododo" (Gẹnẹsisi 15:6).

### Lagbara lati Ṣe e

Ọpọlọpọ ọdun kọja, ṣugbọn Abrahamu "le ni igbagbọ́, o nfi ogo fun Ọlọrun." Abrahamu mọ pe Ọlọrun lagbara lati ṣe ohun ti O ṣeleri. O ti jẹ iyanu tó lati ni iru igbẹkẹle bẹẹ ninu Ọlọrun! Bi a ti n kà nipa Abrahamu ati igbagbọ́ rẹ̀ ninu Ọlọrun eyi ni lati jẹ́ iranlọwọ fun wa lati gbẹkẹle awọn ileri Ọlọrun. Satani n sọ fun awọn ẹlomiran pe Ọlọrun kò ni gba wọn là, pe ẹ̀ṣẹ wọn ti tobi ju Eyi ki i ṣe otitọ. Oluwa wi pe, "Ẹniti o ba si tọ̀ mi wá, emi ki yio ta a nù, bi o ti wù ki o ri" (Johannu 6:17).

Ninu Owe ni a ri ileri aanu kan: "Ẹniti o bo ẹ̀ṣẹ rẹ̀ mọlẹ ki yio ṣe rere: ṣugbọn ẹnikẹni ti o jẹwọ ti o si kọ̀ ọ silẹ yio ri ánu" (Owe 28:13). Ninu Orin Dafidi a kà a pe Ọlọrun yoo gba awọn "onirora" ọkàn tabi ẹni ti o ni ọkàn ironupiwada là (Orin Dafidi 34:18). O le dabi ẹni pe ohun ti ko le ṣe e ṣe ni pe gbogbo ẹ̀ṣẹ eniyan ni Ọlọrun "ki yio si ranti mọ́" (Heberu 8:12) ati pe yoo mu irekọja eniyan jina kuro" bi ila-õrun ti jinna si iwọ-õrun" (Orin Dafidi 103:12), ṣugbọn Ọlọrun ṣe bẹẹ fun awọn wọnni ti o gbagbọ́. Ohun ti Ọlọrun ba ṣeleri O lagbara lati ṣe e.

**Ọmọ Ileri**

Ni akoko kan ni igbesi-ayé wọn nigba ti o dabi ẹni pe ko ṣe e ṣe mọ́, Ọlọrun fi ọmọkunrin kan fun Abrahamu ati iyawo rẹ̀, lẹyin ti wọn ti duro fun ọdun mẹẹdọgbọn. Isaaki jẹ́ ọmọ ileri. Lọna bayii, Ọlọrun bẹrẹ si i mu ipa ti Rẹ̀ ṣẹ ninu adehun ti O ti bá Abrahamu ṣe. Nipasẹ ọmọkunrin kan ṣoṣo yii Ọlọrun gbé orilẹ-ede nla naa kalẹ eyi ti O ti ṣeleri fun Abrahamu. Bi o tilẹ jẹ pe Abrahamu kò fi oju ri orilẹ-ede yii ki o to kú, o gba Ọlọrun gbọ́. Abrahamu gbé ọdun marundinlọgọsan (175) ni ayé. O ṣi wà laaye nigba ti a bi awọn ọmọ-ọmọ rẹ̀ ibeji.

**Messia**

Ọ̀kan ninu awọn ọmọkunrin meji yii, Jakọbu, di baba ọmọkunrin mejila (Gẹnẹsisi 35:22). Awọn ẹbi awọn ọmọkunrin wọnyii ni o di Ọmọ Israẹli -- ayanfẹ Ọlọrun, ani awọn Ju. Ọpọlọpọ ọdun lẹyin eyi, laaarin awọn eniyan ẹya Juda ni idile Dafidi, a bi Jesu –Jesu Olugbala ninu Ẹni ti a o ti bukun fun gbogbo orilẹ-ède!

Abrahamu kò si laye nigba ti Jesu wa laye. Ṣugbọn Abrahamu fi igbagbọ́ fi oju sọna si akoko ti Jesu yoo kú lori agbelebu.

**Ti A Rà**

Jesu gba ipo wa, O si jiya fun awọn ẹ̀ṣẹ wa. O ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ lati san owo igbala wa. Awọn ti o gba Jesu gbọ́ ti wọn si gbẹkẹle E a maa ri idariji gbà. A pa ẹ̀ṣẹ wọn rẹ́ a si fi ododo dipo ẹ̀ṣẹ wọn.

**Ki I Ṣe Iṣẹ**

Abrahamu kò fi owo ra ododo ti rẹ̀. Bakan naa ni ko si ṣe e ṣe fun ẹnikẹni lode oni lati fi owo ra igbala. Jesu ni o san owo naa. Nipasẹ igbagbọ́ ninu Ẹjẹ ti O ta silẹ a maa n nu irekọja wa nù. Abrahamu kò ṣiṣẹ fun ọpọlọpọ ọdun lati ri ododo gbà, gẹgẹ bi a ti i san owo-ọya fun eniyan fun iṣẹ ti o ṣe. Bi o ba jẹ pe nipa iṣẹ ni Abrahamu fi ri ododo gba ni, oun i ba ni ẹtọ lati maa ṣogo nipa iṣẹ ti o ṣe. Ṣugbọn "Abrahamu gbà Ọlọrun gbọ́, a si kà a si fun u li ododo."

Abrahamu ni baba igbagbọ́ -- "baba gbogbo awọn ti o gbagbọ́." Awọn wọnni ti wọn ti ri igbala jẹ́ ọmọ Abrahamu (Galatia 3:7). Awọn ti i ṣe ti Kristi jẹ́ iru-ọmọ Abrahamu ati "arole gẹgẹbi ileri" (Galatia 3:29). Bi Abrahamu ti ni igbagbọ́, bakan naa ni awa ni lati ni igbagbọ́ pẹlu ki a ba le kó ẹ̀ṣẹ wa lọ.

Awọn idile Abrahamu kò jogun ododo. Ododo ki i ṣe ogún ti o n ti ipasẹ Ofin wá. Ṣugbọn "Ọlọrun fi i fun Abrahamu nipa ileri" (Galatia 3:18). Olukuluku eniyan, gẹgẹ bi eniyan kọọkan ni lati ni igbagbọ́ ki o ba le ri igbala ati ododo gbà. Dafidi mọ̀ bẹẹ o si ni iriri yii pẹlu. Dafidi wi pe, "Ibukun ni fun (Ẹni ayọ ni) awọn ti a dari irekọja wọn ji, ti a bò ẹ̀ṣẹ wọn mọlẹ" (Orin Dafidi 32:1). Ọna kan naa ti iwọ le gbà di ẹni ayọ pẹlu, ni yii – nipa fifi Ẹjẹ Jesu bo awọn ẹ̀ṣẹ rẹ̀ mọlẹ. Gba Oluwa gbọ́!

**AWỌN IBEERE**

1 Ta ni kọ Iwe Romu?

2 Awọn wo ni a kọ ọ si?

3 Ta ni Ọlọrun pe jade lati ilẹ Uri ti Kaldea?

4 Ibukun wo ni Ọlọrun ṣeleri fun Abrahamu?

5 Bawo ni Abrahamu ti duro pẹ́ tó fun ọmọ ileri naa?

6 Bawo ni Jesu ṣe mu ibukun wá ba gbogbo orilẹ-ede?

7 Ki ni a kà si ododo fun Abrahamu?

8 Bawo ni eniyan ṣe le ri igbala lọjọ oni?

9 Ta ni a le gbala lonii?

10 Ta ni baba igbagbọ?